# KRISTI, IPILẸ KANṢOṢO

### 1 Kọrinti 3:1-23

### ẸKỌ 390 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ipilẹ miran ni ẹnikan kò le fi lelẹ jù eyiti a ti fi lelẹ lọ, ti iṣe Jesu Kristi" (1 Kọrinti 3:11).**

**Ọranyan ni Lati Ní Ipilẹ Rere**

Gbogbo ile ti a kọ́ lati duro pẹ́ ni a n kọ́ sori ipilẹ ti o lagbara. Bi o ti wù ki ile dara tó, bi a ba kọ́ ọ sori ilẹ lasan tabi lori iyanrin, eniyan diẹ ni iru ile bẹẹ le wù. Iji ati ojo yoo mu ki o sun kuro ki o sán, o si le wó lulẹ. Nitori naa ohun kin-in-ni ti a ni lati rò ninu ile kikọ ni ipilẹ ti o dara

Nigba miiran, a maa n fi ipilẹ rere lelẹ; ṣugbọn bi ọdun ti n yi lu ọdun, ohun kan le ṣẹlẹ ti yoo ba a jẹ́ . Boya awọn igi nla ti a fi kọ ọ dabi ẹni pe o lagbara pupọ nigba ti a gbé wọn sibẹ; ṣugbọn jijẹra tabi ikán ti sọ wọn di alailagbara to bẹẹ ti o fi le rún nigba ti a ba fi ọwọ kan an. Ile yii pẹlu le wo lulẹ, Awọn eniyan ti o ni ẹmi akiyesi a maa yẹ ipilẹ wọn wò lati igba de igba lati ri i pe ohun gbogbo wà ni titọ.

**Ipilẹ Igbagbọ́ Wa**

Nigba ti eniyan ba di Onigbagbọ́ tootọ, ti a tun un bi, Jesu di Ipilẹ Igbagbọ́ rẹ̀. Ko si ohun ti o le ba ipilẹ yii jẹ. Oun jẹ ẹni ti a ti "danwo." O si ti fi ara rẹ̀ hàn bi "okuta igun-ile iyebiye." Nigba kan nigba ti Isaiah sọrọ nipa wiwa Jesu, o wi pe: "Nitorina bayi li Oluwa Jehofah wi, pe, "Kiyesi i, emi gbe okuta kan kalẹ ni Sioni fun ipilẹ, okuta ti a dán wò, okuta igun-ile iyebiye, ipilẹ ti o daju" (Isaiah 28:16). Eyi ni ipilẹ igbagbọ́ wa bi a ba jẹ Onigbagbọ́ atunbi. Niwọn igba ti a ba wà lori ipilẹ yii, kò si ewu. Ohunkohun ko le wó ile wa lulẹ.

**Kikọ́ Ile sori Ipilẹ**

Lẹyin nini ipilẹ ti o daju, a ni lati kọle bi a ba n fẹ lati ni ile, Lati ri igbala nikan kò tó. Boya a le fi iriri wa akọkọ nipa Igbagbọ wé ilẹ-ile. Ko si ẹni ti o n fẹ gbe inu ile ti kò ni ogiri tabi orule. Ilẹ-ile kò tó. Bi a ba kó ohunkohun sori ilẹ-ile, ti a ti fi i silẹ tojo-tẹrun, yoo maa bajẹ bi o ti wu ki a ṣe e daradara tó.

Ni ojoojumọ ayé wa, ninu ohun gbogbo ti a n ṣe, a n kọ ile ni.

**"Ọrọ kọọkan ti o sọ,**
**Iṣẹ kọọkan ti o ṣe**
**N kọ́ ile ayeraye silẹ."**

Onigbagbọ n fẹ lati gbé igbesi-ayé ti o wu Ọlọrun. Oun kò ṣiṣẹ fun erè, ṣugbọn Ọlọrun n kọ wọn silẹ yoo si fi erè fun oloootọ. "Ohunkohun ti ẹnyin ba nṣe, ẹ mã fi tọkàntọkàn ṣe e, gẹgẹ bi fun Oluwa, kì si iṣe fun enia; ki ẹ mọ̀ pe lọwọ Oluwa li ẹnyin o gbà ère ogun: nitori ẹnyin nsin Oluwa Kristi" (Kolosse 3:23, 24).

**Titẹsiwaju ninu Ile-Kikọ́**

Awọn eniyan ti wọn gbagbọ pe bi a ba ti gba wọn là lẹẹkan, awọn jẹ ẹni igbala sibẹ ni gbogbo igba, bi wọn ba tilẹ lọ sinu ẹ̀ṣẹ jẹ awọn ẹni ti ile wọn ko ni laari rara. Igbesi-ayé Onigbagbọ́ jẹ ile ti a ki i dawọ duro ni kikọ́ ki o ba le maa dara ju bẹẹ lọ, ki a si le maa tọju eyi ti a ti kọ́ sibẹ.

Lai si aniani, iwọ yoo ti maa kiyesi awọn ile ti o dara nigba ti a ṣẹṣẹ kọ́ wọn, ṣugbọn ti a fi silẹ lai si itọju fun ọ̀pọlọpọ ọdun. Iwọ ki yoo ri ẹwa lara wọn mọ́. Ọ̀da ara rẹ̀ ti ṣá; awọn ferese rẹ̀ le ti fọ́; ẹrọ omi rẹ̀ n jò; awọn takada ti a fi ṣe ọṣọ sara ogiri rẹ̀ ti kun fun eeri wọn si ti faya. Ko si ẹni ti n fẹ gbe ninu iru ile bẹẹ. Bẹẹ ni ẹni naa ri, ẹni ti n ro pe nitori pe oun ti ri igbala lẹẹkan, oun jẹ́ ẹni igbala bẹẹ titi lai bikita pe oun n ṣe eyi ti o tọ lati mu ki igbesi-aye rẹ̀ gẹgẹ bi Onigbagbọ wà ni ipo daradara.

**Ọmọ-ọwọ ninu Kristi**

Ijọ Kọrinti ti bẹrẹ si i kọle sori Kristi, Ipilẹ tootọ, ṣugbọn wọn ko i ti kọ ile tó bi o ti tọ́ sori ipilẹ wọn. Paulu wi pe ọmọ-ọwọ ninu Kristi ni wọn jẹ sibẹ, nitori naa wara ni o yẹ ki a maa fun wọn dipo onjẹ.

Apọsteli naa sọ fun wa pe eso Ẹmi ni: "Ifẹ, ayọ̀, alaafia, ipamọra, iwa pẹlẹ, iṣore, igbagbọ́, iwa tutu, ati ikora-ẹni-nijanu." (Galatia 5:22, 23). Onigbagbọ aṣẹgun ti o ti dagba ninu ẹmi a maa ni awọn oore-ọfẹ wọnyii ni iwọn ti o ju ti awọn ọmọ-ọwọ ninu Kristi lọ. Bi eso yii ba wa ninu ayé Onigbagbọ́, ki yoo ni ilara, ija, ati iyapa ti Paulu wi pe o wà laaarin awọn ara Kọrinti.

Bibeli sọ fun wa nipa awọn oore-ọfẹ ni ti Ọlọrun n fẹ ki a fi sinu ile-kikọ́ wa. "Ẹ fi iwarere kun igbagbọ́, ati imọ kún iwarere; ati airekọja kún imọ; ati sũru kún airekọja; ati iwa-bi-Ọlọrun kún suru; ati ifẹ ọmọnikeji kún iwa-bi-Ọlọrun, ati ifẹni kún ifẹ ọmọnikeji" (2 Peteru 1:5-7).

Ifẹ ọmọnikeji ni ṣiṣe oore fun ẹlomiran. John Wesley sọ nigba kan pe:

**"Ṣe gbogbo rere ti o le ṣe,**
**Ni gbogbo ọna ti o fi le ṣe e,**
**Ni gbogbo ọna ti o wà nipá rẹ,**
**Nibi gbogbo ti o le ṣe e,**
**Ni gbogbo akoko ti o le ṣe e,**
**Si gbogbo eniyan ti o le ṣe e si,**
**Titi ni gbogbo akoko ti o le ṣe e."**

A ni lati ṣaapọn lati jẹ́ Onigbagbọ́. A ni lati wá isọdimimọ́, ki a le wú gbongbo ẹ̀ṣẹ kuro lọkan wa. Jesu n fẹ awọn eniyan onirẹlẹ lati sin In. O wi pe: "Alabukún-fun li awọn òtoṣi li ẹmi: nitori tiwọn ni ijọba ọrun . . . . Alabukún-fun li awọn ọlọkàn-tutù: nitori nwọn o jogún aiye" (Matteu 5:3, 5).

**Irẹlẹ**

Ọna kan ti o dara lati ṣe alaye irẹlẹ ni pe ki a má ṣe rò nipa ara wa. Awọn ẹlomiran a maa ṣe aapọn lati jẹ ẹni irẹlẹ to bẹẹ ti wọn a maa gberaga pe awọn jẹ́ onirẹlẹ. Ẹni kan ti wi pe "Irẹlẹ ni wiwà ni iwa pẹlẹ ọkàn titi lọ. Irẹlẹ ni wiwà lai ṣaniyan ohunkohun, ki ohunkohun ti a ṣe si mi má ṣe ya mi lẹnu, ki n má ṣe ro ohunkohun nipa ohun ti a ṣe si mi. Lati sinmi jẹẹ nigba ti ẹnikẹni kò ba yìn mí, ati nigba ti a bá ba mi wi ti a si kẹgan mi. Lati ni ibugbe alaafia kan ninu mi nibi ti mo le lọ ki n si tilẹkun ki n si kunlẹ nikọkọ fun Baba mi, ki n si wà ni alaafia gẹgẹ bi ninu omi didakẹrọrọ nigba ti ohun gbogbo ni ayika ati loke jẹ́ idaamu" (Iwe Igbagbọ Apọsteli No.17).

Jesu fi apẹẹrẹ iru irẹle bẹẹ lelẹ. "Kristi pẹlu jiya fun nyin. O fi apẹrẹ silẹ fun nyin, ki ẹnyin ki o le mã tọ̀ ipasẹ rẹ̀: Ẹniti kò dẹṣẹ̀, bẹni a kò si ri arekereke li ẹnu rẹ̀: Ẹni, nigba ti a kẹgan rẹ̀, ti kò si pada kẹgan; nigbati o jiya, ti ko si kilọ; ṣugbọn o fi ọ̀ran rẹ̀ le ẹniti nṣe idajọ ododo lọwọ" (1 Peteru 2:21,23).

Jesu wi pe: "Nitorina ki ẹnyin ki o pé, bi bāba nyin ti mbẹ li ọrun ti pe" (Matteu 5:48). Lẹyin eyi, O kilọ pe, "Ọrọ ti mo ti sọ, on na ni yoo ṣe idajọ rẹ̀ ni igbẹhin ọjọ" (Johannu 12:48); nitori naa a ki yoo ni awawi nigba ti a ba de idajọ. Jesu ti fun wa ni aṣẹ Rẹ̀ nipa bi a ṣe le di Onigbagbọ́ aṣẹgun, O si n fẹ pe ki a kọ́ ile wa sori ipilẹ tootọ ki a ba le de oju ami ti aṣẹ Rẹ̀ beere. Nigba ti a ba sọ ọkan wa di mimọ́, a o maa dagba si i ninu oore-ọfẹ.

**Fifi Ọla fun Ọlọrun, Ki i ṣe fun Eniyan**

Awọn miiran ni Kọrinti fẹ́ ojiṣẹ Ọlọrun kan ju omiran lọ. Awọn kan ti ri igbala nigba ti Paulu waasu fun wọn, bẹẹ ni awọn miiran ti ri igbala nigba ti Apollo wá ṣe ipade pataki laaarin wọn. Ni tootọ wọn fẹran ẹni ti o kọ́ wọn bi wọn ṣe le ri igbala. Ṣugbọn Paulu gbiyanju lati fi hàn wọn pe oun ati Apollo jẹ́ ohun-elo nipasẹ eyi ti Ọlọrun sọrọ. Ọlọrun nikan ṣoṣo ni o le mu ki iṣẹ naa ki o leso.

**Didán Iṣẹ Wa Wò**

Nitori naa gbogbo wa jumọ n kọle ni -- akọkọ, ile ẹni kọọkan wa, ati lẹyin eyi ile Ọlọrun, Ijọba Rẹ̀ ni ayé. A o dán ile wa wò, lati mọ ohun ti a fi kọ́ wọn. Irisi ode ko ni to lati sọ rere nipa wa. "Iṣẹ olukuluku enia yio hàn. Nitori ọjọ na yio fi i hàn, nitoripe ninu iná li a o fi i hàn; iná na yio si dán iṣẹ olukuluku wò irú eyiti iṣe" (1 Kọrinti 3:13).

Oriṣiriṣi ohun elo ni o wà ti a le fi kọ́ ile ti ara. Igi, koriko, akeku koriko jẹ ohun ti yoo jó ninu ina kiakia. O ṣe e ṣe fun eniyan lati tete kọ́ ile pẹlu awọn ohun elo wọnyii, ṣugbọn wọn ki i duro pẹ́. Bi ina ba si kàn wọn, wọn yoo jo kánkán.

Fadaka, wura, ati okuta iyebiye jẹ́ ohun elo ti ki i jó. Wọn ṣọwọn, a si n lò wọn lati ṣe awọn ohun-elo keekeekee. Ṣugbọn wọn a maa wà pẹ́. A le kọ ile Ẹmi wa pẹlu awọn ohun elo ti yoo duro pẹ́, bi a ba le kọ ile wa gẹgẹ bi aṣẹ ti Ọlọrun pa. A ni lati maa gbe igbesi-ayé wa pẹlu iṣọra ki a si maa ṣe ayẹwo nigba gbogbo lati ri i pe a wà lori ipilẹ ni Kristi Jesu. Bi a ba ṣe iṣẹ-isin wa fun Ọlọrun, fun ogo Rẹ̀ nikan, a o fun wa ni èrè. Ṣugbọn ko si bi iṣẹ wa gẹgẹ bi Onigbagbọ ti le pọ̀ to, bi a ba ṣe e lati fi ara hàn ni eniyan mimọ́ niwaju awọn eniyan, igi, koriko, akeku koriko lasan ni iṣẹ wa, yoo si jona.

**Tẹmpili Ẹmi Mimọ**

"Ẹnyin kò mọ̀ pe tẹmpili Ọlọrun li ẹnyin iṣe, ati pe Ẹmi Ọlọrun ngbe inu nyin" (1 Kọrinti 3:16). A ki i ṣe ti ara wa. Awa gẹgẹ bi Onigbagbọ́, a ti rà wá pada nipa Ẹjẹ iyebiye Jesu nigba ti dá wa lare, a sọ ọkàn wa di mimọ́ nipa Ẹjẹ Jesu nigba ti a ni iriri isọdimimọ́; a si di ibugbe Ẹmi Mimọ́ nigba ti a ba ri Ẹmi Mimọ gbà.

Nigba naa a kọ́ ile wa pari; ṣugbọn a le maa fi ọṣọ kun un lojoojumọ lati mu un lẹwa, a si ni lati maa kiyesi irin wa lojoojumọ niwaju Ọlọrun ati eniyan, ki a ba le mu ki ile wa wà ni ipo ti o yẹ.

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni Paulu pe awọn ara Kọrinti? Ki ni ṣe?

2 Ta ni Ipilẹ Igbagbọ́ wa?

3 Bawo ni a ṣe le kọle sori Ipilẹ yii?

4 Oriṣi ohun-elo ikọle meloo ni o wà? Ewo ni o le jóna, ewo ni kò le jona?

5 Ta ni yoo dán iṣẹ wa wò? Nigba wo?

6 Iru iṣẹ wo ni Jesu yoo fi ere fún?

7 Ki ni yoo ṣẹlẹ si iṣẹ ti a ṣe lati wu eniyan?